# AWỌN ASỌTẸLẸ BALAAMU ATI IMỌRAN BUBURU RẸ̀

## Numeri 23:1-30; 24:1-25; 31:8, 16; 2 Peteru 2:12-17

## ẸKỌ 111 – FUN AWỌN ỌDỌ

**AKỌSORI: "Ibukún ni fun ẹniti o ni Ọlọrun Jakọbu fun iranlọwọ rẹ, ireti ẹniti mbẹ lọdọ OLUWA Ọlọrun rẹ̀" (Orin Dafidi 146:5).**

### Ẹwà Ihinrere

Balaki ati Balaamu duro ni ibi giga lori oke nla kan ti o doju kọ ibudo Israẹli. Balaki ti moke nipa mimú Balaamu wá lati fi awọn eniyan Ọlọrun gegun; ireti rẹ si ga -- ṣugbọn yoo bá ijatilẹ pade. Awọn wọnyii jẹ ọmọ Ọga-Ogo Julọ, awọn ẹni ti O fẹran ti O si bukun fun; Balaamu si wi pe, "Emi o ti ṣe fibú, ẹniti Ọlọrun kò fibú? tabi emi o si ti ṣe firé, ẹniti OLUWA kò firé?"

Ni ode oni ọpọ eniyan ni wọn jẹwọ pe ẹwà wà ninu Ihinrere, ti wọn si n jowu iwa ododo awọn eniyan Ọlọrun; ṣugbọn awọn tikara wọn ko ni otitọ inu lati kọ ẹṣẹ wọn silẹ ki wọn si sin Oluwa. Ọlọrun maa n lo iru awọn eniyan bẹẹ lati sọ ọrọ didun nipa ijọba Rẹ; awọn ọkàn tilẹ le ri igbala nipasẹ iwaasu wọn; ṣugbọn iru awọn oniwaasu bayii ti wọn ko ni ifẹ Ọlọrun ninu ọkàn wọn n tan ara wọn jẹ ni; nigba pupọ ẹwẹ, wọn maa n tan awọn eniyan jẹ pẹlu, dipo ki wọn jẹ́ iranwọ fun wọn.

Balaamu jẹ wolii eke ti Ọlọrun lò lati sure fun Israẹli ni aifi awọn ọta wọn pè. Nipa imisi Ẹmi Mimọ, Balaamu sọrọ nipa iṣeun Ọlọrun si awọn eniyan Rẹ̀, o si ké rara pe, "Jẹ ki emi ki o kú ikú olododo, ki igbẹhin mi ki o si dabi tirẹ̀! Ọrọ alarinrin ni wọnyii, Balaamu i ba ti jẹ igbadun lati kú bẹẹ, ṣugbọn ohun ti yoo gba a pọ ju nnkan ti oun n fẹ san lọ. Balaamu fẹ ọrọ̀ aye isisiyii ju bi o ti fẹ Ọlọrun lọ. Lai si aniani, gbogbo eniyan ninu ayé ni o n fẹ lati ri ibukun Ọrun gbà, ṣugbọn wọn ko fẹ gbé igbesi-aye ti o wu Ọlọrun.

### Erupẹ Jakọbu

Balaki ati Balaamu kọkọ ṣe irubọ akọ maluu meje ati agbo meje lori pẹpẹ meje. Nigba gbogbo ni awọn ọmọ Ọlọrun maa n rubọ lori pẹpẹ kan, si Ọlọrun otitọ kan ṣoṣo.

Lẹyin irubọ naa, Balaamu beere lọwọ Ọlọrun ohun ti oun o wí. Lati ori oke yii Balaamu le ri pupọ ninu ibudo awọn Ọmọ Israẹli, o si fi iyanu wi pe, "Tali o le kà erupẹ Jakọbu?" Eyi rán wa leti ileri ti Ọlọrun ṣe fun Abrahamu, ki orilẹ ede Ju to wà rara: "Emi o si ṣe irú-ọmọ rẹ bi erupẹ ilẹ: tobẽ bi o ba ṣepe enia kan ba le kà iye erupẹ ilẹ, on li a o to le kaye irú-ọmọ rẹ pẹlu" (Gẹnẹsisi 13:16). Balaamu ni lati ro pe a ti mu ileri yii ṣẹ nigba ti o ri gbogbo agọ awọn Ọmọ Israẹli. Balaamu tun sọtẹlẹ pe awọn Ọmọ Israẹli yoo dá gbé, a ki yoo si ka wọn kun orilẹ-ede; fun ọpọlọpọ ọgọrun ọdun sẹyin titi di oni Ju ni Ju n jẹ́.

O dun Balaki pupọ pe ifiré ti oun ti daba yipada si ibukun ṣugbọn o mu Balaamu lọ si ori oke miiran, o si wi pe ki o tun sọtẹlẹ. Lati ibẹ kiki apa kan ibudo ti o wà nitosi ni o le rí, boya Balaki si ro pe bi ko tilẹ ju iba awọn eniyan diẹ ti ọna wọn jìn, o le fi wọn bú, ṣugbọn Balaamu tẹnu mọ ọn pe kiki ohun ti Ọlọrun ba gba oun láyè lati sọ ni oun le sọ.

### Awọn Ẹni Ibukún Ọlọrun

Ọlọrun ti sure fun Israẹli ná, O sọ fun Balaamu nisisiyii pe Oun ki yoo yi ipinnu Oun pada. O fẹran Israẹli nitori laaarin wọn ni a gbé orukọ Ọlọrun otitọ leke. "Ibukún ni fun awọn enia na, ti ẹniti Ọlọrun OLUWA iṣe" (Orin Dafidi 144:15).

Ko si ibi ti o le de ba awọn Ọmọ Israẹli niwọn igba ti wọn ba n gbọran si Alaṣẹ wọn. Lati igba de igba ni Ọlọrun sọ fun wọn pe bi wọn ba pa gbogbo ofin Oun mọ́, ko si ibi kan ti yoo ṣubu lù wọ́n. "Yio si ṣe bi iwọ ba farabalẹ gbọ́ ohùn OLUWA Ọlọrun rẹ, lati ma kiyesi ati ṣe aṣẹ rẹ̀ gbogbo ti mo pa fun ọ li oni, njẹ OLUWA Ọlọrun rẹ yio gbé ọ ga jù gbogbo orilẹ-ède aiye lọ" (Deuteronomi 28:1). Ohun aigbọdọ ma ṣe kan ṣoṣo ti o wà ni pe ki wọn gbọran si Ọlọrun lẹnu. Gbogbo orilẹ-ede iyoku jẹ alailagbara lori wọn bi wọn ba pa Ofin Rẹ̀ mọ. Rò ti ọla ati ogo ti i ba wà lori Israẹli bi o ba ṣe pe, lati igba naa wá ni wọn ti fẹran Ọlọrun pẹlu gbogbo ọkan wọn! Dipo eyi nitori aigbọran wọn a mu wọn kaakiri agbaye, lai ni ilu tabi asia, fun nkan bi ẹgbaa (2000) ọdun. Ni ọdun 1948, ni akoko ti wa yi, ni wọn ṣẹ̀ṣẹ̀ tun di orilẹ-ède.

### Ibukun N Pọ̀ Si i

Inu bi Balaki ni ipari ọrọ Balaamu lẹẹkeji to bẹẹ ti o fi wi pe bi Balaamu ko ba le fi Israẹli bú ki o ma ṣe sure fun wọn rara. Ni tootọ Balaamu fẹ fi Israẹli bú, nitori a ka a ninu Joṣua 24:10, pe Ọlọrun wi pe, "Emi kò fẹ́ fetisi ti Balaamu; nitorina o nsure fun nyin ṣá."

O dabi ẹni pe titi di akoko yii, Balaamu ti n gbiyanju lati lò ninu agbara okunkun rẹ̀ atijọ, ṣugbọn nisisiyii o wa jọwọ ara rẹ lọwọ patapata lati jẹ ki Ọlọrun tipasẹ oun sọrọ. Ọrọ ti o sọ jade si ti larinrin to! O sọ bi o ti ṣe gbadun

agọ awọn Ọmọ Israẹli ti wọn tò lẹsẹlẹsẹ.  O sọtẹlẹ nipa ogo ati agbara ọjọ iwaju ti yoo jẹ ti awọn ogun wọn bi wọn o ti jade lọ lati bori awọn ijọba; o ṣeleri ibukun fun awọn ti n sure fun Israẹli, ati ifibu lori gbogbo awọn ti o ba fi wọn bú.

Balaki gbiyanju lati pa Balaamu lẹnu mọ, o si le e jade kuro ni ilu rẹ.  O wi pe oun tilẹ rò lati gbé Balaamu ga ninu ọrọ̀ ati ọla-nla, ṣugbọn Oluwa fa a sẹyin kuro ninu rẹ̀.  Balaamu mọ ni ti Oluwa pe ko si bi ọrọ̀ ti le pọ tó, ki i tilẹ ṣe ile ti o kunfun fadaka ati wura, ni o le yi ipinnu Ọlọrun pada lati fi ègún sori awọn eniyan ti Oun fẹ sure fun.  Ju bẹẹ lọ paapaa, Balaki ki ba ti le fun Balaamu ni nnkan kan bi Ọlọrun ko ba ti pese rẹ̀ silẹ.

**Nipa Jesu**

Dandan ni ki a sọ ọrọ Ọlọrun, Balaamu si tun sọrọ lẹẹkan si i.  Ni akoko yii asọtẹlẹ rẹ̀ jẹ ti ọjọ ti o jinna réré, ṣugbọn wọn jẹ asọtẹlẹ ti ko ni ṣai ṣẹ dandan.  O sọ ti Irawọ ti yoo ti inu Jakọbu jade wá, ati Ọpa-Alade ti yoo ti inu Israẹli dide. Eyi n sọ nipa Jesu ti yoo wá bi Irawọ ireti fun awọn ti aye ti tẹ̀ mọlẹ.  Yoo ti inu ẹya Juda jade wa, yoo si “là, ti on ti imularada ni iyẹ́-apá rẹ̀” (Malaki 4:2).  Malaki tun sọ nipa rẹ bi “Õrùn ododo.”  Nigba ti Simeoni gbé Jesu gẹgẹ bi ọmọ-ọwọ́ le apá rẹ̀, ni akoko ti awọn obi Rẹ̀ gbe E wá sinu Tẹmpili, o pe E ni “imọlẹ lati mọ́ si awọn Keferi, ati ogo Israẹli enia rẹ” (Luku 2:32). Jesu yoo mú imọlẹ ati iye wá fun gbogbo ẹni ti o ba gba A gbọ́.

Ọpa-Alade jẹ ami aṣẹ, apa kan asọtẹlẹ yii n sọ ni ti akoko ti Jesu yoo tun pada ti yoo si jọba pẹlu ododo fun Ẹgbẹrun (1,000) ọdun ni aye yii.  Ko si ọba buburu ti yoo le doju kọ Ọ.  A n pe akoko naa ni Igba Ijọba Ẹgbẹrun Ọdun.

**Idalẹbi Balaamu**

Balaamu ti sọ ọrọ̀ ribiribi nipasẹ imisi Ọlọrun, ṣugbọn wọn ko ṣe e ni anfaani kankan nitori ọkan rẹ̀ buru.  Paulu Apọsteli sọ fun ni pe, “bi mo tilẹ nfọ oniruru ede ati ti angẹli, ti emi kò si ni ifẹ, emi dabi idẹ ti ndún, tabi bi kimbali olohùn goro” (1 Kọrinti 13:1).  Balaamu ko ri ere kankan gbà fun awọn ibukun ribiribi ti o sure rẹ fun Israẹli.  Ninu 2 Peteru 2:17, a ri ere ti o wà fun awọn eniyan kan lara ẹni ti Balaamu jẹ ọkan: “Awọn wọnyi ni kanga ti kò li omi, ikũku ti ẹfũfu ngbá kiri; awọn ẹniti a pa òkunkun biribiri mọ́ de titi lai.”  Kò si àye fun awọn eniyan iru bẹẹ ni Ọrun: “Ohun alaimọ́ kan ki yio si wọ̀ inu rẹ̀ rara, tabi ohun ti nṣiṣẹ irira ati eke; bikoṣe awọn ti a kọ sinu iwe iye Ọdọ-Agutan” (Ifihan 21:27).

**A Jẹ Abọriṣa Israẹli Niyà**

I ba ṣe pe Balaamu ti pada lọ si ile rẹ̀, Israẹli ki bá ti ni ipalara rara ninu ète Balaki lati fi wọn ré.  Ṣugbọn o ni ọna ti o ṣe arekereke ju bẹẹ lọ lati fi mú wahala wá sori awọn ọmọ Ọlọrun.  Igba kan ṣoṣo ti a le bori awọn Ọmọ Israẹli ni, nigba ti wọn bá dẹṣẹ si Ọlọrun wọn.

Balaamu fun Balaki ni imọran eyi ti o mú ki ọpọlọpọ ninu Israẹli wá sin awọn ọlọrun ajeji awọn ara Moabu.  Ibinu Ọlọrun si ru si awọn eniyan Rẹ̀, ajakalẹ-arun si pa ẹgbaa mejila (24,000) nitori ibọriṣa wọn.  A ko gbọ́ nipa Balaamu mọ titi awọn Ọmọ Israẹli fi lọ bá awọn ara Midiani jà.  Ọlọrun fun awọn eniyan Rẹ̀ ni iṣẹgun, laaarin awọn ọmọ-ogun ti a ṣẹgun rẹ̀ ni a ti ri Balaamu ti a si pa a (Numeri 31:8).

**AWỌN IBEERE**

1. Ki ni ṣe ti ohun ti Balaamu sọtẹlẹ kò tẹ́ Balaki lọrun?
2. Nibo ni Balaamu ti ri ọrọ ti o sọ?
3. Darukọ asọtẹlẹ ti o sọ nipa Israẹli.
4. Ninu wọn ha ti ṣẹ bi?  Sọ diẹ ninu wọn.
5. Eniyan meloo ni o kú nipasẹ amọran Balaamu?
6. Ki ni opin Balaamu?